# ILANA Isodotun fun deede O
# Orilede Naijiria (NGP)
# Ọdun 2021-2026

## Atileyin Ajo

MacArthur
Foundation

Ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin

# ILANA
# Isodotun Deede fun Obinrin Orilede Naijiria (NGP)Ọdun 2021-2026



MacArthur Foundation

*Atunse nipasẹ*
*Ajo fun Idabobo Eto ati Ilosiwaju Awọn Obinrin (WRAPA)*

*Ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin*

*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*

**ILANA ISODOTUN DEEDE FUN**
**OBINRIN ORILEDE NAIJIRIA (NGP)**
**ỌDUN 2021-2026**

Aṣẹkiko © (WRAPA)
A se Atẹjade Iwe yii Lorilede Naijiria ni ọdun 2023

Ko gbodo si atẹjade, fifpamo si aye atunte tabi tan kaakiri ni eyikeyi ọna, yala nipa ero ayarabiasa,eda-sise, gbigbasilẹ pelu ero gbohun-gbohun, tabi ona miran, lai gbase ati iyonda lowo Ajo to se Agbekale Iwe yii; ayafifun ayolo awọn ọrọ kukuru ati asamo ninu iwe iroyin, tabi iwe atigbadegba, ati awọn lilo ti kii ṣe ti owo sise nikan ni a gba laaye labe ofin aṣẹ-kiko iwe yi.



MacArthur Foundation

ISBN: 978-978-780-610-4

*Atunse nipasẹ*
*Ajo fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obinrin (WRAPA)*

*Pelu ifowosopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin*

*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*

# ATỌKA AKORI


| | |
|---|---|
| IJEWO | v |
| ORO AKOSO | vi |
| ORO ISAAJU | vii |
| AKOSO | viii- x |
| ORO AKOSO | xi - xii |

IDI ETO AMULO AJOSEPO TO GUNMO LAARIN OKUNRIN PELU OBINRIN Oju-iwe 1

KOKO AYO ORO IKINI: ISOFIN ATI ETO ORO Oju-iwe 2




MacArthur Foundation

*Atunse nipasẹ*
*Ajo fun Idabobo Eto ati Ilosiwaju Awọn Obinrin (WRAPA)*

*Pelu ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin*

*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*

KOKO AYO ORO IKEJI: IROLAGBARA ORO-AJE, ABAJADE ATI ONA IJEE-MU Oju-iwe 4

KOKO AYO ORO IKETA: IDAGBASOKE EDA ENIYAN Oju-iwe 12

KOKO AYO ORO IKERIN: GEESI NINU AWON ILE-ESE TO N RI SI ORO AWUJO OMONIYAN Oju-iwe 26

KOKO AYO ORO IKARUN: GEESI NINU AWON ILE-ISE TO N RI SI EKA AABO Oju-iwe 34

KOKO AYO-ORO IKEFA: GEESI NI IGBALAYE SI EKA IDAJO, ETO OMONIYAN ATI ISEJOBA. Oju-iwe 41

KOKO AYO-ORO IKEJE: GEESI, ISE-ASIWAJU, ATI IKOPA NINU OSELU. Oju-iwe 47

KOKO AYO-ORO IKEJO: GEESI, IWUWASI, ASA ÀTI ISE Oju-iwe 53

Ajo fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obinrin (WRAPA) Pelu ifowosowo Ile-Ise Ijoba fun Oro Obinrin Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.

# Ifọwọsi

A gbagbo pe Irin-ajo ẹgbẹrun maili ni o bẹrẹ pẹlu igbesẹ kan. Irin-ajo imulo Eto fun irorun Obinrin Orilede Naijiria (NGP) 2021 - 2026 bẹrẹ pẹlu atilẹyin, idurosinsin ati ifowosowopo ti Ijọba orilẹ-ede Nàìjíríà lati ṣe agbega imudogba okunrin ati obinrin ati itesiwaju awọn ẹtọ awọn obinrin. Afokansi ijọba Nàìjíríà fun aseyori erongba yi ni opa kutele fun siseto idagbasoke atiimuse ilana ise-deede okunrin ati obinrin ti Orilẹ-ede Naijiria.

WRAPA fie mi imoore tooto han si Ile-iṣẹ Ijoba Apapo to n se Akoso oro Awon Obinrin Igbimọ; ati Pataki julo Hon. Minisita oro awon obinrin Dame Pauline Tallen, CON, OFR, KSG, fun idari. Itọnisọna ati imọran ti oludari ti Ẹka Okunrin-Obinrin; nipasẹ atunse Eto fun Irorun Obinrin Orilede Naijiria; atunse yii lo ka ilana yii ye fun imulo ati siso di gbajugbaja fun lilo gbogbo omo Naijiria. Imo ati iriri kikun lori oro awon obinrin; lo se iranlowo fun akanse ise ajumose Ajo WRAPA-FMWA NGP.

WRAPA moriri atilẹyin, iduro sinsin, inure ati ifowosowopo ti Ajo MacArthur Foundation ni Naijiria; fun gbigba lati ranwa lowo lati se iwe Ilana fun Igbelaruge deede larin okunrin ati Obinrin Orilede Naijiria ni ona to ma wulo fun gbogbo omo Naijiria; a mo riri imọran ati aduroti won lori akanse ise yi. Iranlọwọ owo,oye ati aduroti lori gbogbo ipade pelu awon iko lorisirisi lati se afikun, agboye, ifaramo, ipinnu ati atileyin fun iwe Ilana yii; awon akanse ipade yii je ona lati je ki iwe Eto yi wulo fun gbogbo eya, esin ati ede to wa lorilede yii ati je atewogba fun gbogbo omo orilede Naijiriati jẹ ohun elo lati jẹ ki ilana pipe ti awọn ifaramọ onipinu si ọna olokiki ati irọrun ti iwe ilana imulo to ṣe pataki fun igbega isedeede okunrin ati obinrin. A ko gbọdọ madarukọ Dokita Amina Salihu, Igbakeji Oludari Ajo MacArthur Foundation, fun akitiyan, abojuto ati atilẹyin imọ-ẹrọ lati ibere de opin sise iwe Ilana fun Irorun Obinrin Orilede Naijiria. (NGP)

Ọpẹ Pataki fun iko akosemose eyi ti Ojogbon Olabisi Aina kosodi sise lori akojopo Iwe Ilana fun Isedeede laarin Obinrin ati Okunrin Orilede Naijiria; a mo riri imo, ogbon, iriri, iduro-sinsin, asiko, ifarada ati ise-akikanju won lati je ki iwe ilana yii je atewogba fun gbogbo eniyan. A dupe lowo Atinuke Odukoya, Temitope Banso, Amina Alhassan ati Victor Ibim Boma fun ise takuntakun ti won se lori akanse iwe yi.

A dupe pupo lowo awon igbimo alajumosisepo lori akanse eto to n se igbelaruge isedede ati akoyawo eto Idibo eyi ti Ajo WRAPA se akoso re pelu atileyin Ajo MacArthur Foundation (Improving Electoral Integrity and Accountability (IEIA); Awon Ajo to wa ninu Igbimo yi ni ; Ajo Akanse Owo fun awon Obinrin (Nigerian Women Trust Fund (NWTF), Ajo Alagbawi, olofintoto ati alakosile oro obinrin (Women Advocates Research and Documentation Centre (WARDC), Ajo awon Obinrin Oloselu (Women in Politics Forum (WiPF), Akojopo Obinrin (100 Women Group), Yan Obinrin Sipo (Elect Her) Ajo To n wa Aseyori Obinrin (National Coalition on Affirmative Action – NCAA) GERCON pelu Eka to n ri si ise deede laarin okunrin ati Obinrin (Gender Technical Unit – GTU) A ko gbagbe ipa ti awon omo Igbimo Alajumosepo lori akanse eto to n se igbelaruge isedede ati akoyawo eto idibo ko ni Ipinle, Ajo to n ri si ihuwasi ati akosile isesi omoniyan (Civil Resource Development and Documentation Centre – CIRDOC) Ajo Alagbawi Naijiria ( Advocacy Nigeria) Ajo Kebetkache Olofintoto ati Alakole (Kebetkache Research and Documentation Centre), Ajo Obinrin to n ri si Ibaraenisoro ni Agbaye (Women International Communication Centre – WICC) ti won je ki Iwe Ilana fun Igbelaruge Isedeede Okunrin ati Obinrin de gbogbo ileto ati igberiko lorilede Naijiria.

Akitiyan awon osise Ajo fun Idabobo Eto ati Ilosiwaju Awon Obinrin (WRAPA) si Iwe Ilana fun Igbelaruge Isedeede Okunrin ati Obinrin; lona lati je ki amulo e rorun fun gbogbo eniyan; pelu ise takuntakun won lori Akanse Ise Igbimo to n ri si Igbelaruge Isedeede ati Akoyawo Eto Idibo. A gbe osuba okare fun awon akosemose wa ti Wumi Asubiaro Dada je adari won; pelu iranlowo Anisah Ari, Oluwayemisi Nathaniel, Zainab Abdurasheed, Paul Adama, Habiba Ahmed, Jovita Chehchet, ati Shafi'u Barde. Emi ifokansin, Ifarabalẹ, iduro sisnsin ati ifowosowopo won lo se okunfa aseyori akanse ise yi.

Nikẹhin, Ajo fun Idabobo Eto ati Ilosiwaju awon Obinrin (WRAPA ) fi imọriri rẹ ti o jinlẹ han si gbogbo awọn ti o ti ṣe alabapin si aseyori Ilana fun Igbelaruge

Isedeede Okunrin ati Obinrin Orilẹ-ede Naijiria (NGP) 2021-2026 gẹgẹbi irinṣẹ patakifun iyipada awujọ Naijiria si eti o si ṣe atilẹyin awọn ẹtọ ati ije-omoluabi gbogbo eniyan.

**Saudatu Mahdi MFR**
**Akowe gbogboogbo**
**Ajo fun Idabobo Eto ati Ilosiwaju Awọn Obinrin (WRAPA)**

*Atunse nipasẹ Ajo fun Idabobo Eto ati Ilosiwaju awon Obinrin*

# Ọrọ Iṣaaju

Ajo MacArthur Foundation labe akanse Ise fun Ile Nàìjíríà dunnu lati ṣe atilẹyin fun Ilana Igbelaruge Isedeede Okunrin ati Obinrin (NGP) ti Nàìjíríà 2023. A ti n tele awon nipasẹ atilẹyin awon osise fun Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin. Bakanna ani iwuri ati igbekele ninu iwoye Ajo fun Idabobo Eto ati Ilosiwaju awon Obinrin (WRAPA) ti o je okan ninu awon alabasisep wa; fun agbekale eto fun ifowosowopo, ilaniloye ati pinpin iwe-ilana fun gbogbo awon eniyan fun ilaniloye ati agboye fun sise amulo ilana yi ni gbogbo awujo.Pataki julọ ninu awon akanse ise wa ni Orilede Nàìjíríà ni bi idoko-owo ati atileyin wa yoo ṣe mu ilosiwaju ba igbesi aye awọn omoniyan ti osi pelu aini n yo lenu. A ni amodaju nipa ayewo awon iwe- akoole ati akiyesi pe, ti awon obinrin ati awon omobinrin ba ri iranlowo idokowo ti won nilo, aseyori won daju eyi a si se okunfa ibasepo alaafia laarin okunrin ati obinrin, aseyori, igbega okowo, irorun ati igbaayegbadun fun awujo ati ilu won.

Ilana Amulo je awon eto atonisona lori awon erongba ati isesi to le mu alaafia ati irorun ba igbesi aye awon eda to n gbe ninu osi ati aini. Ailowosi ijoba sise, ailagbara, jije ako tabi abo, aigbajumo ninu awujo le se okunfa osi ati aini. O se ni lanu pe awon obinrin ati odobinrin lo po ju ninu awon alaini ni awujo. Eyi gan lo fa ayolo ede Otosi ni Obinrin, toripe aini ati osi han julo lara awon obinrin ju okunrin lo; ati paapaa iwadi ti fidire mule pe ti won ba ko alaini merin sile; meta ninu won le je Obinrin. Ifonrere Ilana fun Igbelaruge Amulo Isedeede larin okunrin ati obinrin je ipepe fun idagbasoke ati ilosiwaju awujo; ki tgbogbo eniyan pelu awon obinrin ati awujo le je anfaani gbogbo anfaani to le fa ilosiwaju, aseyori, alaafia ninu okowo ati igbaye gbadun. Botilejepe Ilana Amulo ati Ofin se koko; sugbon won o to lati fa ayipada ti a fe; won le je igbese akoko lona a ti de ebute ogo. Ofin ati Ilana Amulo je ona lati mo erongba ijoba; lati beere eto wa. Lati je ki Ilana Amulo yi wulo; awon olujere amulo yi gbodo se oju lalakan fii sori lori gbogbo eto ati ise awon Asofin ni Ile Asofin Agba ati Ipile kowa won; lati maa se agbeyewo ije-olooto lori awon ofin ti won n se fun gbogbo wa; ati ofin to le mu igbayegbadun ati ilosiwaju ba awon obinrin. Ati alaafia gbogbo eniyan ati awujo lati maa se igbelaruge ati ibeere loore-koore lori imulo, bawo lo se n lo, ni Orilede ati ni Ipinle. Awon aseyori ati ilosiwaju wo lo ti wa nipase amulo Ilana yii; pelu awon ona ti awon ayipada otun se le di ayipada lailai ni awujo wa; pelu akiyesi awon ibi ti ipenija tun wa lori Ilana Amulo yii pelu awon ofin to n se ironilagbara ati ilosiwaju fun awon obinrin.

Awọn koko Pataki kan wa ti a gbodo pe akiyesi e, onka akoko olodun marun 2021-2026; eyi fi anfaani sile lati tesiwaju nipa agbekale, lilo, ipolongo, akiyesi ati ayewo Ilana Otun fun Igbelaruge deede larin okunrin ati Obinrin yii fun odun Marun Akoko. Eyi a fun wa ni anfaani lati se akopo akiyesi, ero ati isesi awon ara ilu lori isamulo Ilana Pataki yi; boya awon akojopo akiyesi ati ero awon ara ilu yii le gbawa ninu wahala ti amojukuro odun merindinlogun lara Ilana Amulo Akoko ti odun 2006 da sile; ki a to beere atunse ni odun 2022. Eyi si ko akude ba amulo Ilana Pataki yii. Ile Ise Ijoba Apapo Lori Oro Obinrin (FMWA) kopa Pataki gegebi Adari awon ohun-Elo fun Imuse-deede okunrin ati obinrin ati igbelaruge eto imunimora gbogbo eniyan ninu awujo;pelu gbogbo eka Ile Ise, Ajo ati Igbimo Ijoba Apapo. Ile Ise Ijoba Apapo Lori Oro Obinrin (FMWA) se koko ninu irin ajo yii; ki I se toripe Ile Ise yii je Amin igbagbo Orilede Naijiria ninu deede laarin okunrin ati obinrin ati imunimora gbogbo eniyan awujo laifi eya, ede, ako tabi abo se. Ile-Ise Ijoba Apapo Lori oro Obinrin je eri fun akitiyan Ijoba Apapo fun deede ako/abo.
A gbodo iranti ikilo Ajo Agbaye fun Idagbasoke Awujo; to so pe amuse deede ako/abo wa ninu ewu. Atunse keta yi je ede ati ede oyinbo, ede abinibi ati aworan fun agboye gbogbo eniyan.

Kole Ahmed Shettima

The John D, and Catherine T. MacArthur Foundation
Abuja
Oludari Afirika

*Atunse nipasẹ*
*Ajo fun Idabobo Eto ati Ilosiwaju Obinrin (WRAPA)*

*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*

# Oro Akoso

Bi a ṣe n ṣe ayẹyẹ iṣẹlẹ pataki ati imuse aniyan wa: Atunse Ilana fun Igbelaruge deede larin okunrin ati obinrin ti Orilẹ-ede Naijiria - NGP fun Akoko 2021 si 2026, Mo fẹ lati gbóríyìn fún H. E. Ààrẹ Muhammadu Buhari, GCFR fún àtìlẹ́yìn rẹ̀ lori ìmúṣẹ ìlànà náà. Ifenuko awọn ẹlẹgbẹ ninu Igbimọ Alase Apapo Orilede Naijiria jẹ ẹri siisekoko deede larin ako ati abo gegebi ona gbogi fun ise ijoba rere ati Ilosiwaju awujo ati Orilede.

Fun okunfa aseyori; mo fe se afihan atileyin ati afokansin Ile Ifowopamo Ile Afrika (ADB), Ajo MacArthur Foundation ati gbogbo awon Atinileyin fun eto Idagbasoke; Atileyin won je igbese Pataki fun iranlowo aseyori yi; won si tun se iranlowo fun omoniyan laifi ije ako tabi abo se lati se aseyori ninu erongba won.

Fun igba pipe, ni a ti n se igbiyanju fun awujọ nibiti gbogbo eniyan le ṣe rere, A ti se aseyori ninu erongba yii botilejepe ise si ku pupo lati se. Atunse Ilana yii je ohun elo ti a maa se ayewo re loore koore lati fi je olumona fun awujo ati ojo-iwaju alajumose, onideede ati eyi ti ko faramo ireje. Ilana yi mo Pataki awon okunrin ati odo-kunrin gegebi alajosepo ninu ilakaka wa fun igbelaruge deede larin ako ati abo. Ilana yi tun se adayanri awon isoro ti awon obinrin ati odo-binrin n koju; beeni Ilana yi tun tenumo idi Pataki lati se imukuro gbogbo awon iwa, asa, ise, eko to je inira ati ifiyajeni fun awon obinrin ati awon omobinrin wa; Ilana yi tun se atenumo iwulo ki a se deede lori ipese eko iwe, eto ilera ati eto okowo ati oro aje fun fun awon okunrin ati obinrin; beeni Ilana yi tun se igbelaruge kikopa awon obinrin ninu akoso ile-ise, awujo ati iselu Orilede; ni imoriri imo ijinle, ogbon atinuda pelu oye ti awon obinrin ni lati dasi ofin sise oro Iselu.

Bi a ṣe gbaruku ti a si n pe fun imuse ati imulo Ilana yii, a gbọdọ ranti pe aseyori Imuse deede laarin ako ati abo pe fun ajumose gbogbo wa ati ajosepo laarin Ijoba ati awon Ajo ti kii se ti Ijoba, Ile-Ise Aladani, awon Ajo Afowo se Iranlowo Eto Idagbasoke ati awon ajo to n pepe fun Idagbasoke Awujo; lati ma kaare nipa sise atileyin imudogba ako ati abo ninu Ile-Ise, Ile-Iwe ati awujo. Mo pea won alakoso Ile-Ise Ijoba, Eka-Ijoba (MDAs) ebi, awujo, awon eyan to lenu ni awujo ati gbogbo ara Ilu lati lo Atunse Ilana yi fun ara won; ki won o si gbaruku ti amulo re fun ilosiwaju awujo ati Orilede.

Mo Gbe osuba kare fún Ajo fun Idabobo Eto ati Ìlọsíwájú Awon Obìnrin (WRAPA) àti gbogbo àwọn tí wọ́n ṣiṣẹ́ kára lori Atunse Ilana fun Igbelaruge deede Ako ati Abo. Idurosinsin yin fun igbesoke deede ako ati abo ati Idajo ododo ni awujo je ohun iwuri. Awon omo Orilede Naijiria n fojusona fun ise eda Atunse Ilana yi ni ede ibile wa ni Orilede Naijiria; ki Ilana yi le di gbajugbaja laarin gbogbo eniyan ni ilu nla ati ese kuku; ki gbogbo wa le parapo lati pe fun imuse ati Imulo Ilana laarin odun Marun 2021-2026.

Dame Pauline K. Tallen, CON, OFR, KSG
Minisita fun oro Awon Obinrin
2023



MacArthur Foundation

*Atunse nipase*

*Ajo fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obirin (WRAPA)*

*Pelu ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin*

*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*

# Ọrọ Iṣaaju

Atunse Ilana fun Igbelaruge deede laarin ako ati abo odun 2021 mo riri pe awon obinrin ni isoro lori isedeede pelu awon okunrinni nitori asa, ihuwasi awujo, ije-akanda, ipo-oro-aje pelu igbe-aye ti ko dara to ni igberiko, agbo-ile, sise-atipo nitori idite awon agbesunmomi, isele pajawiri ati wahala awon ajinigbe, awon janduku ati ajakale arun. Ile–Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin (FMWA) ni ojuse lati maa se eto fun idagbasoke ati ilosiwaju awon obinrin ati okunrin pelu; nipa sise awon akanse eto fun isemi, igbayegbadun, aabo, ilosiwaju ati ikopa ti gbogbo eniyan, paapaa awọn ti aṣa ni agbegbe eti eto idagbasoke orilẹ-ede.

Awon obinrin, Omode, arugbo, awon akanda eyan ati awon eyan miran to nilo aabo ninu ifiyajeni laileto ati iyanje ni won wa ni ipele akoko oluje-anfaani eto Ile-Ise Ijoba Apapo fun Obinrin.

Ilana fun Igbelaruge deede Ako ati Abo ti o jade ni odun 2006 ti ṣe iranlọwọ ni ọpọlọpọ awọn ọna; nipa pipe akiyesi awon eniyan si eto awon obinrin ati odo-binrin pelu awon ti iya gidi n je lawujo wa. Ijoba kede ifaramo Ilana yii, sugbon imuse lerefe lo se okunfa pipe gbogbo awujo lati gbaruku ti Ilana yii. Eyi se Pataki toripe awon oro to kan igbaye-gbadun awon obinrin bi irolagbara lori ise ati okowo, eto eko, eto ilera, eto amayederun ati jije asiwaju ati didi ipo mu ninu oro iselu agbegbe ati Orilede ni akude ba.

Pelu pe awọn obinrin fe to idaji awọn olugbe; ati Ida Ogota awon Oludibo ni Nàìjíríà (Ajo Agbaye fun Obinrin, 2O19), alafo tun foju han gbangba lori yiyan obinrin ni asoju lori oro-ilu, nipa sise akoso oro-ilu ati awon eto ironilagbara fun okowo ati awon eto ilese-danu.

iii o se koko lati faramo awọn ilana atunyẹwo oorekoore; lati maa wadi bi ẹrọ ti a ṣe sinu ninu eto imulo titele ati Etoimuse iṣẹ, sise odiwon ilọsiwaju, kọ ẹkọ, ati se agbeyewo awon ogbon ati ilana tuntun.

iv Awọn amuye to ṣafihan awọn alafo aisedede okunrin ati obinrin ni Nàìjíríà; ni akawe si awọn orilẹ-edemiiran, eyi yoo fi aaye sile lati pe akiyesi ijoba.

v Awọn ababo oro lori aisedede okunrin ati obinrin; fun afiwe Afojusun Idagbasoke Agbaye (SDGs); igbese yi nilo awon akanse Ilana ni ibamu pelu awon afojusun onidagbasoke miran ni agbaye.

Fun idi eyi, Ile-Ise Ijoba Apapo fun Awon Obinrin (FMWA) pelu ajosepo Ajo fun Idabobo Eto ati Ilosiwaju Awon Obinrin (WRAPA) ati awon Ajo Alabasisepo miran (CSOs) sise po lati se ayewo Ilana fun Igbelaruge deede larin okunrin ati obinrin ni odun 2021; a se akojo aba, afikun, imoran ati ayokuro; a gba ase lati se Atunse Ilana yi lodo Igbimo Ijoba Apapo to ga julo (FEC) ni Osu Keta 2022; eyi lo fa ikojade Ilana yi. A se eto ilaniloye fun awon egbe elesin, Oniroyin, Awon Oba, Awon Olori Esin, Awon Eleto Abo, Awon Eleto-Idibo lati wa atileyin ati ifowosowopo won fun amulo Ilana yi.

A se ikede Lori redio, ero mohunmaworan ati lori ayelukara ni a ti n se ipolongo lati je ki gbogbo awujo mo nipa Ilana yi fun atileyin ati imulo re. Aare Orilede Naijiria Ogagun Feyinti Muhammed Buari se alaye pe Atunwo Ilana fun Imusedeede larin okunrin ati obinrin jẹ lilo lọwọlọwọ lati pe akiyesi Ile-Ise Ijoba, Awon Ajo ti ki se ti Ijoba, Awon Egbe Elesin ati Asa pelu gbogbo eto ijoba lati se amulo deede larin okunrin ati obinrin ninu ise ati ise-akoso won. Eyi se Pataki fun ilosiwaju ati idagbasoke awujo.

*“Ideyesi obinrin ati awọn ọmọbirin ni awọn ile-iṣẹ Ijoba ati ti Aladani n kowa lominu. Obinrin ati Okunrin, Omọbirin ati Omọkunrin, ati awọn ti a Deyesi gbodo ni Asoju ninu Isejoba ati gbogbo awujọ ki ala won le di mimuse.*

**A nilo amojuto ati ifowosowopo lati se aseyori gegebi oro ti Minisita Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin-Dame Pauline Tallen, CON,OFR, KSG:**

> ***Ni arin imulo Ilana yi ni Akikanju,***
> ***Eleti-gbaroye ati Olujiyin Orilede***
> ***Ati Ajo Oluwoye***

**Fun Idi eyi Ajo fun Idabobo Eto ati Ilosiwaju awon Obinrin (WRAPA) pelu Awon Ajo ti awon Obinrin n se adari won; pelu atileyin Ajo MacArthur Foundation se afihan idi fun Atunse Ilana fun Igbelaruge deede larin okunrin ati obinrin si ona ti o rorun fun agboye awon eto Ilana ko le je iwulo fun gbogbo eniyan; a fi asiko yi pe gbogbo eniyan lati fowosowopo pelu wa lori amulo ati imuse Ilana yi fun idagbasoke awujo ati Orilede wa.**

*Ajo fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obinrin (WRAPA)* *Pelu Ifowosowopo Ile-Ise Ijoba fun Oro Obinrin* *Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*

# AKỌRỌ

**AfCFTA:** Agbegbe Iṣowo Ọfẹ ti Afirika

**AIDS:** Aisan Kogbogun

**CBOS:** Awọn Ajo Igberiko

**CEDAW:** Apejọ fun Imukuro Gbogbo Awọn Iwa Iyasotọ Awọn Obirin

**COVID 19:** Arun Coronavirus ti ọdun 2019 CSOs: Awọn ajọ awujọ

**CSR:** Ojuse Atileyin awon Ile-Ise Aladani fun Idagbasoke Awujo

**EFCC:** Igbimọ To n ri si sise Owo-Ilu ni Moku-moku

**EWER:** Ikilọ ni kutukutu ati idahun ni kutukutu

**GBV:** Awon iwa ifiyaje ati Asilo Obinrin

**GEESI:** Idogba akọ-abo, ironilagbara awon obinrin, ati imumora gbogbo eniyan.

**HIV:** Kokoro Aarun Eedi

**ICPC:** Awọn Igbimo Ijoba to n sise fun idekun iwa Ibaje

**ICT:** Imọ-ẹrọ Ibaraẹnisọrọ

**IDPs:** Awọn eniyan to n se Atipo

**INEC:** Igbimọ idibo olominira Naijiria

**INGOS:** Awọn ajo Okeere fun Idagbasoke

**LGA:** Agbegbe Ijoba Ibile

**MDAS:** Awọn Eka ile-iṣẹ Ijoba

*Ilọsiwaju Awọn Obinrin (WRAPA)* *Pelu ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Awon Obinrin* *Atilẹyin nipasẹ MacArthur Foundation.*

**MSMEs:** Awon Ile-Ise Okowo Kekere

**NAFDAC:** Eka Ile-Ise Ijoba Apapo fun Idiyele Ounje ati oogun

**NBTE: Eka Ile-Ise Ijoba Apapo fun Eto**

**NEMA: Eka Ile-Ise Ijoba Apapo fun Akoso Isele Pajawiri**

**NGO:** Ajo ti kii ṣe ti ijọba

**NGOS:** Awọn Ajo ti kii ṣe ijọba

**NGP:** Ilana imulo deede ako/ abo orilẹ-ede Nigeria

**NOA:** Eka Ile-Ise Ijoba Apapo fun Ilaloye Ara-Ilu

**NUC:** Igbimọ ile-ẹkọ giga ti Nigeria

**PLWHA:** Eniyan to Ngbe pẹlu kokoro Arun Eedi

HIV/AIDS**PWD:** Awọn akanda eniyan to n gbe pelu kokoro arun eedi

**PWDs:** Awọn Akanda Eniyan.

**S/GBV:Iwa** Ibalopo-pelu-ipa ati ifowo-kanni-laileto

**SEMA:** Ile-iṣẹ Iṣakoso pajawiri ti Ipinle

**SURE-P:** Akanse Eto fun Ilo-Owo Iyasoto fun Idiyele fun Ironilagbara Awujo

**UNHCR:** Igbimọ giga ti Ijoba Agbaye fun Abo Eto

Omoniyan

**UNSCR:** Ipinnu Igbimọ Aabo Agbaye

**VAPP:** Akanse ofin fun imukuro iwa Ipa

**VAW:** Iwa-ipa si obinrin

**FỌ:**

*Atunse nipasẹ Ajo fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obinrin (WRAPA)*

*Pelu Ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin*

*Atilẹyin nipasẹ MacArthur Foundation.*

# Kilofa Ilana NGP?

**Ilana fun Igbelaruge deede larin Okunrin ati Obinrin ni Naijiria (NGP) ni ona lati se deede larin okunrin ati obinrin, ironilagbara fun obinrin ati eto Ifayegbani Lawujo (GEES) ninu ilana ati eto ni Ile-Ise ijoba ati ti Aladani ni Orilede Naijiria. Nitorinaa Orilede Naijiria a di awujo ti obinrin, okunrin, omobinrin ati omokunrin yoo mo gbadun anfaani, eto ati ojuse kan naa.**



*Atunse nipasẹ*
*Ajo fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obirin (WRAPA)*
*Ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obirin*
*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*
MacArthur Foundation

# KOKO PATAKI IKINNI:
# OFIN ATI ILANA

## IPO TI A WA:

1. Ofin 1999 (atunse) ko se eto deede obinrin ati ọkunrin.



2. Ilana Ideyesi obinrin si wa ni ile-ise ijoba ati ti aladani



3. Ofin Ifiya je enikeni to ba huwa ipa VAPP (2015) ti di lilo ni Ipinle merinlelogbon, sibe iwa ipa ati idiyaje obinrin si n po si ni awujo wa.



Ajo fun Idabobo Eto ati Iḷọsiwaju Awọn Obinrin (WRAPA) Pelu Ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.

# Igbese To Ye:

1. Je agborandun fun Ilana ati ifesemule deede 50:50 fun idibo ati yiyan awon eniyan sipo ni Naijiria.
2. Je agborandun fun ofin to tako asilo ati ilokulo obinrin CEDAW ni agbegbe re.
3. Se amulo deede larin okunrin ati obinrin ninu ise akanse ni gbogbo awujo
4. Se idanileko fun awon osise Ijoba ati aladani lori amulo deede; ati eko nipa sise eto isuna to ni anfaani fun obinrin.
5. Gbiyanju lati ni eto fun idanileko awon obinrin nipa jije olori.
6. Se koriya fun awon ti won ba tele ofin deede larin okunrin ati obinrin; fiya to to je arufin
E se eto idanileko fun awon adajo ati awon agbofinro lori deede laarin okunrin ati obinrin
7.

## Awon Ti Oro Kan

Ile-Ise Ijoba fun oro Obinrin ati awon Eka Miran toro kan

Gbogbo Ara Ilu

Awọn ẹgbẹ Alagbawi ati awọn Ajo Aladani

Awon Ajo To wa fun Idagbasoke



Atunse nipasẹ
Ajo fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obinrin (WRAPA)
Pelu Ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin
Atilẹyin nipasẹ MacArthur Foundation.
MacArthur Foundation

# KOKO PATAKI KEJI:
# IROLAGBARA OKOWO, ISE-SISE, ATI ETO IGBESI-AYE

## (A)Eto-Ogbin ati Idagbasoke igberiko

### Ipo Ti a Wa:

Awon Obinrin to le ni Ida

**Ogota ninu Ogorun**

lo n sise agbase ninu oko; sibe sibẹni opin wiwọle si olu, ilẹ, ati awọn orisun pataki miiran.



### Awọn iṣe ti o nilo:

1. Ki Ijoba Apapo ati Ipinle ki won se afihan ati piparun awon asa aitegbe ati alafo to wa laarin okunrin ati obinrin; pelu awon akanda eyan (PWDs) to wa ninu ise agbe.

2. Fi awọn ilana ti o fun gbogbo agbe laiya enikenisoto ni anfaani si awon akosemose oludanileko nipa ise agbe; ki awon agbe le se ibeere ati ofintoto lori gbogbo awon ohun to ruwon loju nipa ise won.



*Atunse nipasẹ*

WRAPA

FEDERAL MINISTRY OF WOMEN AFFAIRS

MacArthur Foundation

*Ajo fun Idabobo Eto ati Ilosiwaju Awon Obinrin (WRAPA)* *Pelu Ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin* *Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*

3. Pese awon ero igbalode ati awon akosemose onimo-ero fun awọn obinrin agbe fun ipese ere-oko ni opo yanturu, ipese ise ati alekun owo to n wole fun awon obinrin agbe.

4. Se alekun imo fun ikojọpọ iroyin lori awọn ọkunrin, obinrin, ati awon akanda (PLWD) to n sise agbe; ati eka ise-agbe ti won wa.

5. Ṣe igbelaruge ajọṣepọ laarin awon agbe to wa ni abele pelu awon akegbe won ni orilede agbaye fun ajosepo lori ise agbe.

## Awọn Ti oro kan

Ijọba Apapo ati Ipinle

Igbimo Olumojuti Eka Ise Agbe ni Ile Asofin Agba ati Ile Asofin Asoju.



Awon Ile-Eko Giga fun Ise-Agbe,

Awon egbe agbe ni Orilede, Ipinle ati ibile.



Ile-Ise Ijoba fun Ise-Agbe ati idagbasoke Igberiko, Ato, Isuna, Obinrin ti Ijoba Apapo ati Ipinle.

*Atunse nipasẹ*
*Ajo fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obinrin (WRAPA)*

*Pelu Ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin*

*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*

## (B). Awon Aladani (Ti kii ṣe Ise-Agbe) Laala Bi

### Bi a Se wa

1 Ipese Ise ni eka ti kii se fun akosemose ni Naijiria je Ida Ogota si Okandinlogorin fun awon obinrin. Sugbon awon okunrin lo n sise ni eka Akosemose ati Ise Ijoba ni eka Apapo, Ipinle ati Ibile.

Ogot



2 Awọn ofin iṣẹ ni Nàìjíríà ko daabobo obinrin nibi asa ideyesi to n sele nile Ise.

3 Awọn obinrin po julo ninu ise okowo kereje; amo awon okunrin po pupo ninu ise idokowo alabode ati Ile-Ise to tobi.

ogorun

### Igbese fun Itesiwaju

1 Fi awọn akolekan obinrin ati ọkunrin, ọmọbirin ati ọmọkunrin, pelu awon akanda eyan si gbogbo eto awon agbanisise ni orilede Naijiria.

2 Ṣe iwuri ati koriya fun awon awọn Ile-Ise ti won n se iranlowo fun awon obinrin, okunrin, odokunrin, odobinrin ati awon akanda eniyan ati awon olokowo alabode ninu akanse eto irolagbara ti awon Ile-Ise naa n se fun awon ara-ilu (CSR)

*Atunse nipasẹ*
*Ajo fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obinrin (WRAPA)*

*Pelu Ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin*

*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*

3. Ṣe awọn ipolongo ati awọn iṣe-akanse fun atunyẹwo awọn ofin Igbanisise ati imulo eto to n pe fun deede larin okunrin ati obinrin, irolagbara awon obinrin ati igbalaye gbogbo awujo laifi ije ako tabi abo tabi akanda eniyan se (GEESI).

4. Se igbedide Ilana deede fun ipese ise fun okunrin ati obinrin lati ma fi aye gba ojusaaju ati idena.

5. Pese agbegbe to rorun ni Ile-Ise lati fi aye gba deede larin awon osise okunrin ati obinrin.

6. Se atileyin fun iyansipo awon obinrin Ida Ogota ninu Ogorun si awon igbimo to n se iranlowo fun awon Ile-Ise Alabode ati Ile-Ise Nla.

7. Rii daju pe iyansipo awon obinrin Ida Ogota ninu Ogorun si awon Igbimo to se koko se agbelewon okunrin si obinrin, Agbegbe, Eya, Ije-Akanda ati Esin laimoju kuro nibi ije akosemose ati piperegede ninu eko ati iriri awon ti a fey an sipo.

8. Se igbedide atilẹyin fun ikopa awọn obinrin ninu akanse eto fun Ise-okowo ni agbegbe Iṣowo Ọfẹ ti Afirika (AfCFTA).

## Awọn Ti oro Gberu

Ijọba Apapo ati Ipinle

Ile-Ise Ijoba Apapo fun awon obinrin ati Awon Eka Ile-Ise Ijoba Apapo.

Awọn ẹgbẹ alagbawi ati Oludabobo ẹtọawọn obirin ati gbogbo egbe to n pe fun ilosiwaju awujo.

Awọn Ile-Ise aladani.

Ile-Igbimo Asofin Apapo



WRAPA

MacArthur Foundation

*Atunse nipasẹ*
*Ajo fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obinrin (WRAPA)*

*Pelu Ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin*

*Atilẹyin nipasẹAjo MacArthur Foundation.*

© Ile-Ise Idaraya ati Amuludun

## Ipo Ti a wa :

1. Awọn Ilana fun awọn işẹ ere idaraya deyesi si ikopa ati ilowosi awọn obinrin, fun işakoso ati sisan owo-oya awon akopa.

2. Eka Amuludun ni anfaani lati se koriya fun ayipada rere lori awon asa, eto ati ise ti ko bojumu to fun ilosiwaju awujo.

3. Awon okunrin ni won di eka Amuludun mu, won ni owo ju awon obinrin lo; eyi lo n se okunfa asilo obinrin fun igbelaruge ise won.

## Awọn Igbese to kan:

1. Şe agbekale Ilana fun isedeede ikopa obinrin, okunrin, omokunrin, omobinrin ati awon akanda eyan ni eka Idaraya ati amuludun.

2. Ri daju pe ipolongo ati ipolowo Ere Idaraya ati Amuludun ko deye si obinrin ati akanda eniyan.

3. Se idanileko fun awon oludari ati igbimo ere idaraya ati awon oniroyin lori oro deedee larin okunrin ati obinrin.

*Atunse nipasẹ*
*Ajo fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obirin (WRAPA)*

*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*

4. Ṣe agbekalẹ Ilana ti o fun gbogbo eniyan, obinrin ati ọkunrin, ọmọbirin ati ọmọkunrin, ati awon akanda eniyan ni anfaani kan naa awọn ninu ere idaraya ati awọn eka amuludun

5. Rii daju pe ko si asilo ede tabi oro ideyesi ninu agbekale ati ipolongo eka ere-idaraya ati amuludun.

6. Se idanileko fun awọn igbimo ati awon olusakoso ere-idaraya ati eka amuludun pelu awon oniroyin lori sise deede larin okunrin ati obinrin.

## Awon Ti Oro Kan

Ijoba Apapo ati Ipinle

Awon Ajo To n ja Fun Ilosiwaju Awujo

Ile-Ise Ijoba Apapo to n sise lori igbelewon

Awon Oniroyin

Ile-Ise Ijoba Apapo fun Ere-Idaraya ati Amuludun

Awon Ile-Ise Aladani



*Atunse nipasẹ*
*Ajo fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obinrin*

*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur*

MacArthur Foundation

## (C). Ișẹ Itọju ebi Ti a ko sanwo fun ati Oro-aje Idile

### Ibi Ti a Wa:

1. Ko si imoriri fun ise ti awon obinrin n se fun idile; gegebi ise okowo ti a le se kun fun ilosiwaju awujo.

2. Ojuse obinrin bi iya n se iranlowo fun idagbasoketi akapo ise orilede; sugbon ko si amulo ise obinrin fun idile ninu akole ati eto igbaradi fun oro-aje orilede.

3. Awujo n se afojudi ati aimore fun Ise itoju Kolowoninu ti obinrin n se fun idile.

### Igbese Fun Ayipada

1. Awọn ẹgbẹ alagbawi Awọn obinrin lati șișẹ pẹlu awọn oniroyin lati jabo ise obinrin ninu idile pelu amuye ilana deede, irolagbara awon obinrin ati igbalaye gbogbo eniyan ninu awujo lai fi ije-ako-tabi-abo se, tabi jije akanda eniyan (GEESI)

2. Ki awọn idile kọ awọn ọmọkunrin ati awọn ọmọbirin ni aṣa ti ibọwọ fun ara-eni.

3. Șe ipolongo ati agbawi fun amukuro awon asa iyanisoto si awọn obinrin ati awọn ọmọbirin ni awujo wa.

4. Se atileyin ati agbawi fun Ilana asiko isinmi fun awon okunrin ti iyawo won sese bimo ni gbogbo eka Ile-Ise Ijoba, Aladani ati awon Ile-Ise ti n pepe fun ilosiwaju awujo.

*Atunse nipasẹ*
*Ajo fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obirin (WRAPA)*

*Pelu ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin*

*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*

5. Ki Ijọba ati awon Ajo To N Pe fun Atunse Awujo se afikun ipolongo ki eto ifetosomobibi wa ni arowoto gbogbo idile.

6. Awọn Oludasile Ile-Iroyin ati awon Ajo To N pe fun Imuduro Awujo, Ijoba, Ile-Ise Adani ati awon Ajo Alatileyin Idagbasoke Awujo tera mo awon eto imuaye derun fun ilosiwaju Orilede.

## Awon ti Oro Kan



- Ijọba Apapo ati Ipinle.
- Awọn Ajo to n pe fun Idabobo eto awon Obinrin pelu awon Ajo to n pe fun Imuduro ati idagbasoke Awujo ati Orilede



- Awọn idile



- Ile-Ise aladani
- Ile-Ise Iroyin
- Awọn Ajo Oluranlowo Idagbasoke Awujo

1

2

3

4

# KOKO ORO KETA: IDAGBASOKE OMONIYAN

**Awon omo wewe jiya orisirisi asilo; bi o tile je pe Ilu wa ni akanse ofin fun idabobo awon omo wewe ti odun 2003; ati pe Ijoba Apapo tun ni akanse ilana fun idagbasoke Imudara ọmọde (IECD) ti ọdun 2007.**

## Awọn Igbese to Kan:

**Gbe Ilana deede larin omokunrin ati omobinrin fun eto Ilera Orilede Naijiria**

**A gbodo dojuko Ilana ati eto lori Ibalopo, ibimo ati ilera molebi pelu atileyin awon Ajo fun Idagbasoke Awujo.**

**Ṣe awọn ipolongo eto ifetosomobibi ati fifi aaye sile laarin omo bibi ni ede abinibi.**

**Ṣeto idasile awọn ile-iṣẹ Afisun iwa ifipa-banilopo (SARCs) ati awon ile pajawiri fun awon obinrin ti won fipa balopo.**

*Atunse nipasẹ*
*Ajo fun Idabobo Eto ati Ilosiwaju Awọn Obirin (WRAPA)*

*Pelu ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin*

*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*

5. Se idasile awon Ile Afisun iwa ifipa-banilopo ni awon igberiko; ati ipolongo fun awon akanse ajo to n koro oju si ifipa-banilopo (CVASGBV) ni igberiko.

6. Ṣe eto awon ohun elo ti o wulo fun Ile Afisun iwa ifipa-banilopo lati ṣiṣẹ bi oludahun akọkọ ti o lagbara ni asiko rogbodiyan.

7. Ṣe idokowo awon irugbin asaralore ti a le papo mo eto ounje ile-iwe awon omode; ati fun eto ogbin ni igberiko.

8. E se ifeloju  Eto ounje Ile-iwe to n samulo awon ounje asaralore to wopo ni agbegbe kookan yika orilẹ-ede

## Awon ti oro Kan

**Ijọba Apapo ati Ipinle**



Ile-Ise Ijoba apapo ati Ipinle fun Ilera, Eto Eko, Awon Obinrin ati Omoniyan, Ile-Ise Akoso Ajalu ati Ile-Ise Idagbasoke awujo.

**Awon Ajo fun Idagbasoke Awujo**



**Awon Ajo Alatileyin Idagbasoke lati Ile Okeere**

Eka Ijoba Apapo to n mojuto Eto Ilera alabode ati ese-kuku.



WRAPA
FEDERAL MINISTRY OF WOMEN AFFAIRS
MacArthur Foundation

*Atunse nipasẹ*
*Ajo fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obirin (WRAPA)*

*Pelu ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin*

*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*

## (B). Eto Ilera ibisi/aarun Eedi/CoVID-19

### Ipo ti a wa:

1. Awọn obinrin ati awọn ọmọbirin, awọn akanda eniyan, awọn are/alejo ati awọn eniyan ti n se atipo,awọn ọmọde ati awọn ọdọ, arugbo, awon elesin, awon sako-sabo, awon eniyan to je ko-sako-ko-sabo, ati awọn eniyan to n gbe pẹlu kokoro eedi (PLWHA) gbogbo awon eyan wonyi lo wa ninu ewu abuku, eebu ati iyanisoto.
2. Awọn obinrin ati awọn ọmọbirin ni ewu pupo lati ko kokoro arun eedi.
3. Àìsàn ọpọlọ àti ìwa isekupara-ẹni ń pọ̀ sí i láàárín àwọn ọ̀dọ́ àti àwọn tó wà ní ipò ola láwùjọ; iwa yi ni nkan se pelu ipo ti oro aje orilede.
4. Orilede Nàìjíríà jẹ́ ìda meta-din –die nínú ọgọ́rùn àwọn olùgbé gbogbo agbaye; ṣùgbọ́n ìdá ogun nínú ọgọ́rùn awon obinrin to n ku ninu oyun tabi asiko ibimo ni Gbogbo Agbaye n sele ni Orilede Naijiria nikan.

### Awon Igbese to Kan:

1. Agbeyewo awọn ofin ti o rọmọ ilera ibisi ati iwa ipa ati ifiya je awon obinrin fun atunse.
2. Se aridaju amulo awọn ilana deede larin okunrin ati obinrin ninu awon eto ilera..

*Atunse nipasẹ*
*Ajo fun Idabobo ati Ilọsiwaju Awọn Obnirin (WRAPA)*

*Pelu ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin*

*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*

3. Se ayewo eto isuna ati awon aseyori inawo.

4. Se ikopa ninu erongba olojo pipe fun eto ilera to le koju isoro awon obinrin ati okunrin.

5. Se ayipada ipe pajawiri fun eto ilera ti orilẹ-ede Naijiria

6. Ijọba ati awon Ajo to n pe fun idagbasoke awujo tera mo ipolongo eto ifetosomobibi ati wiwa ni arowoto awon ara ilu.

7. Se akojobo iwadi ati atupale lori ibalopo / akọ; pelu awọn irinṣẹ amuseya fun awon mekunnu.

8. Se idanileko fun awọn oṣiṣẹ ilera lori deede larin okunrin ati obinrin fun eto ilera

9. Se afikun ẹ̀kọ́ ìbálòpọ̀ tako-tabo kún ètò eko ile-iwe ati awon akanse eto miran lawujo fun adinku oyun laarin awon omobinrin.

## Awọn alabaṣepọ Lodidi

ijọba Apapa ati ipinlẹ

Ile-Ise ijoba Apapo ati ipinlẹ fun akoso Ilera, eto Ẹkọ ati oro obinrin

Awon Ajo to n pe fun idagbasoke awujo

Ile Asofin Apapo

Ajo awon Akosemose Eleto Ilera.

Ajo to n se amojuto awon ile eko giga.

Awọn Ajo Alatileyin Awujo ati idagbasoke lati okeere



*Atunse nipasẹ*
*Ajo fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obirin (WRAPA)*
*Pelu ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin*
*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.* MacArthur Foundation

## (C). Eto Ilera Iya ati Ọmọ / Idagbasoke Ọmọde

### Ipo Ti a Wa:

1. Awon Obirin ni orile-ede Naijiria n koju isoro pupo lori awon eto igbayegbadun

2. Pelu ọpọlọpọ awọn awon akanse eto ilera, iku awon obinrin n po si ni asiko iloyun ati ibimo, eyi jinna si imuse afojusun SDG3; oni gbedeke iku obinrin to kere si aadorin ninu egberun-lona-Ogorun obinrin to ye lasiko iloyun ati ibimo ti asiko 2030.

3. Awọn obinrin lati igberiko ati/tabi lati Ariwa Naijiria wa ninu ewu ti o ga julọ ni asiko iloyun ati ibimo; ni akawe si awọn egbe won to wa ni igboroati/tabi Gusu Naijiria; eyi ri be nitori isoro asa, ise ati igbagbo awon ara igberiko pelu aisi ile-iwosan ati itoju to peye ni igberiko.

### Igbese To ye

1.

2. Ki Ijọba ati awon ajo to n pe fun idagbasoke awujo mura si ilaniloye lori eto ifetosomobibi ati ikede awon Ile-Iwosan to wa ni itosi won.

3. Se alekun ipolongo ati idanileko lori itoju awon omo- kekere ati abere ajesara

Ṣe agbeyẹwo awọn ilana ilera lati se dede pelu ohun to sele ni agbaye fun itoju iya ati omo.



MacArthur Foundation

*Atunse nipasẹ*
*Ajo fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obinrin (WRAPA)*

*Pelu ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun oro Obinrin*

*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*

4 Ki awọn Ajo to n pe fun idagbasoke awujo ati ijọba sise papo se agbekale eto ilera to le je itewogba gbogbo eniyan pelu ifowosowopo awon ti o je anfaani eto yi.

5 Lo awọn ẹkọ aseyori eto SURE-P; eto owo amoriya ti Ijoba fun iyalomo ati alaboyun lati lo si Ile-Iwosan fun itoju oyun ati omode; eyi mu ayipada rere ba bi awon aboyun ati awon iyalomo se n lo Ile-Iwosan lasiko; ki Ijoba Apapo se agbedide eto owo amoriya yi fun awon obinrin, omode
6 ati awon akanda eniyan.

7 Ṣe alagbawi fun afikun eko isedeede larin okunrin ati obinrin ninu eko awon ile-Iwe lati alakobere de Ile-eko giga.

Ṣe alekun iwadi awon ona lati se işiro akọ-abo fun imulo; ati iseto amaratuni kiakia fun awon alaini.
8 Se idanileko fun awon akosemose ni eka ilera lori ilana deede larin ako ati abo fun imuseya lori eto ilera.
Se afikun eko nipa deede larin ako ati abo si eko iwe nile iwe alakobere ati giga; pelu eko awujo fun awon odo.

## Awon ti oro kan

Ijoba apapo ati Ipinle



Awon Ajo to n pe fun idagbasoke awujo

Awon Ile-Ise Ijoba Apapo ati Ipinle fun ilana eko,ilera ati oro obinrin.

Igbimo Ijoba Apapo fun eto ilera Alabode ati awon Ajo okeere Alatileyin fun Idagbasoke Awujo



*Atunse nipasẹ*
*Ajo Fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obinrin (WRAPA)*

*Pelu ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin*

*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*

## (D) Ihuwa Ako ati Abo ati Eto Systems

**Bo se ri bayi**

**Eto ilera to wa lowolowo ko ni ilana ati awon ohun elo lati se amojuto iyato to wa lori ipese ilera to kun oju osunwon fun okunrin tabi obinrin.**

**Igbese To Kan:**

1. **Ṣe eto ilera kan ti yo mu adinku ba iṣoro to ro mo ilera awọn idile, paapaa awọn obinrin bi to je alamojuto idile.**
2. **Ijọba gbodo se irolagbara eto ilera alabode to wa ni ijọba Ibile (LGA) ati awọn adugbo lati gbe igbese fifi alaisan sowo si ile iwosan miran fun itoju to peye,**
3. **Ṣe akoso awọn akole to ye fun ọkunrin ati obinrin, fun oniruru aisan ati oro ilera.**
4. **Awọn Alatileyin fun idagbasoke lati ilu okeere gbodo tẹsiwaju lori sise atokun Ijoba fun igbaradi, ati amojuto awon eto fun ilera kariaye.**
5. **Ijọba lati fowosowopo pẹlu awọn ẹgbẹ ẹlesin lati ṣe ipolongo ati ilaniloye lori awọn oro to kan ilera; lati mu opin tabi adinku Ba iwa ideyesi awon eniyan ti won n gbe pelu kokoro arun eedi ati awon ipenija to jeyo ninu ibalopo ako ati abo, ni Pataki julo awon to kana won obinrin.**

*Atunse nipasẹ*
*Ajo fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obirin (WRAPA)*

*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*

Se alekun owo ti won yasoto fun eka ilera fun igbadun awon obinrin ati lati se koriya fun awon osise ilera gegebi o se wa ni awon orilede agbaye.

Ṣe agbekalẹ awọn ilana ati eto lati se igbelaruge aṣa deede ni gbogbo ile-iṣẹ ati eka ijoba, aladani, ati agbegbe lori oro ilera, ounje ati isoro ibaraẹnisọrọ.

Awọn Ajo ti oro kan

Ijọba Apapo ati Ipinle

Awọn Ajo aladani.

Ile-Ijoba Apapo ati Ipinle fun Ẹkọ, Ilera, ati oro awon Obinrin

Awon Igbimo fun eto ilera kariaye.

Awon Ile-Ise Aladani

Awọn Awujo

Awon Ajo Ilu Okeere Alabasisepo fun idagbasoke

*Atunse nipasẹ Ajo*
*Fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obinrin (WRAPA)*

*Pelu ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin*

*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*

## (E). Aseyori Eto Ẹkọ ati Iṣẹ-owo pelu imo Igbesi aye

### Ipo ti a wa:

1. Alekun ti ba iye awon omo to n kuro nile-Iwe laiti pari eko won, papa julo larin awon obinrin, nitori oyun-apete
2. Ko rorun fun imuse ilana eko fun Imudogba akọ-abo, Irolagbara Awọn Obirin, ati Ikonimora Awujo (GEESI) ninu asa wa,
3. Awon obinrin lo n se pupo ninu ise-ile eyi ko n funwon laaye lati mojuto idanwo amuwalewon.

### Awọn Igbese to ye:

1. Gbaruku ti iforukosile awon omobinrin nile-eko; so ikiri oja fun awon omode die sun odaran; se atileyin owo fun awon obi to je alaini.
2. Lo Ilana deede larin omojunrin ati omobinrin se amojuto ati igbelewon aseyori Ile-iwe, iforukosile awon akeko ati awon to n s anile-iwe
3. Ṣe apero, idanileko ati iranlowo ohun elo fun igbedide deede larin ako ati abo pelu igbalaye gbogbo awon omode sinu alakale eko fun awon akeko ni gbogbo ile-iwe lorilede Naijiria
4. Se koriya fun awọn obinrin/awọn ọmọbirin lati yan ayo ninu eko imọ-jinlẹ ati imọ-ẹrọ.
5. Lo imọ-ẹrọ fun igbelaruge awon obinrin/ọmọbirin ninu ẹkọ ati imo
6. Ṣe afikun idokowo ninu imọ-ẹrọ ati ẹkọ ẹkọ iṣẹ-owo

*Atunse nipasẹ*
*Fun Idabobo Obinrin ati Ilọsiwaju Awọn Obirin (WRAPA)*

*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.*

7. Se afikun idokowo si eka eto-ẹkọ fun ikopa awọn ọmọbirin, awọn akanda eniyan ati awọn ọmọde to wa lati idile awon obi alaini.

8. Rii daju pe deede wa laarin okunrin ati obinrin ti won je omo-igbimo alakoso ile-eko fun amuse deede larin awon akeko.

9. Ṣe akosile awon iwa aseyori fun awokose awon ile-eko miran

10. Se amuse ilana deede larin okunrin ati obinrin ni gbogbo eka eto-eko ni Orilede Naijiria.

11. Ṣe ojusaju fun igbelaruge eto-eko igberiko ati eko-agba fun awon ọkunrin ati obinrin.

12. Ṣe amuse deede larin awọn obinrin ati ọkunrin fun eto-ẹkọ ile-iwe giga ati se ise to wuyi lawujo.

## Awọn Ti Oro Kan

Ijoba Apapo ati ipinlẹ



Ile-Ise Ijoba apapo ati ipinlẹ fun Eko, Ilera ati Oro awon Obinrin



Awon Ajo fun Idagbasoke Awujo

Awọn obi ati awọn idile.





*Atunse nipase Ajo fun Idaboo Eto ati Ilọsiwaju Awon Obinrin (WRAPA)*

*Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur*

MacArthur Foundation

## (F). Eka Idabobo Awujo

### Ipo Ti a Wa:

1. Lasiko ti a wa yi wahala wa fun omoniyan ni Orilede Naijiria, nipasẹ ija ati ogun to n sele laarin awon ilu ti won mule tirawon, pelu iwa-ipa, jagidi-jagan ati ajalu to n sele latari iyipada oju-ojo, omiyale gbogbo-igba ati awọn ilana ọwọ-lile ti Ile-Ise Ologun n gbe lati dekun iwa-odaran lawujo wa.

2. Wahala igbogun-ti-ara-eni lóríl̀ẹ-èdè yii ti dé ọ̀dọ̀ àwọn Agbẹ̀ ati awon Fulani ti n da malu, iwa janduku ati iwa Ijinigbe awon ara Ilu; eyi to so gbogbo ara ilu sinu iberu ati ipayinkeke.

3. Awọn obinrin ati awọn ọmọde lo n faragba julo ninu wahala ati idamu to n sele yii, toripe won jiya iwa ifipabanilopo, iwa asilo, iwa-ipa (GBV) ati igbeyawo ọmọde.

4. Orilede Nàìjíríà lo wa ni ìpo kokanla nínú awon Orilede ni Agbaye to n fi omodebinrin loko; won si wa ni Ipo keta ninu awon orilede lágbàáyé to ni awon obinrin to ti di iyawoki won to pe omo odun mejidinlogun.

### Igbese To Kan

1. Se itesiwaju ninu iwadi lati mo awọn okunfa iwa-ipa, awọn amuye to fa ailagbara, ati awọn ipa ti awon nkan-ijagun keekee to n po si le ni lori alaafia awujo ati awon obinrin.

2. Ṣe iwadi alaisegbe ki awon Ile-Ise Awakusa san owo-gba-ma-binu fun awọn Ilu to Ni awon alumoni inu-ile ni gbogbo Igba ti wahala idoti ati iwa iteetoeni loju ba sele.

3. Se eto-idanileko ati ilaloye lori aburu to ro mo ifilule-salo-silu-miran, ipese iranlowo fun awon to ba fe filu-sile-lo-si-ilu-miran ati irolagbara awon eka Ijoba fun ajosepo to dara.



WRAPA
Federal Ministry of Women Affairs
MacArthur Foundation

Atunse nipasẹ Ajo fun Idabobo Eto
Ati Ilọsiwaju Awọn Obinrin (WRAPA)

Pelu ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin

Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.

Ṣe afikun ipin ọlọpa-si-eniyan fun ise abo to munadoko ati idanileko ati sise koriya fun awon ọlọpa ti n ṣiṣẹ labẹ awọn eto ise-anu ti n ṣẹlẹ nipasẹ ija.

Ṣe agbekalẹ owo-akanse fun awon to farapa ati awon to ni adokujo nibi ija; ati awon osise olugbani-nimoran fun alaafia okan ati opolo, lojuona ati tete bo sipo lati tesiwaju ninu igbesiaye won.

Se Irolagbara Awọn ile-iṣẹ Isafisun esun Ifipabanilopo (SARCs) ni gbogbo awọn ipinlẹ fun itoju awon awon ti oro kan.

Se itẹnumọ́ ilera ọpọlọ, ẹ̀dùn-ọkàn, ihuwasi ninu awujo, àti ìtọ́jú ẹ̀mí, Mura si idaduro iwa ideyesi fun awon eyan to ni arun opolo; pese eto idanileko fun eyan to ni arun opolo lori ona a ti ri iwosa

Ṣe itesiwaju awon eto Ijoba to wa fun irolagbara lati din osi ati aini ku ni awujo; apẹrẹ awon eto Ijoba bi eto akanse owo-fun-awon-alaini.

Se eto ibasisepo pelu awon Olori ijo elesin tokunrin-tobinrin ati awon Oba Alaye fun imayederun ati itọju awon alaini ni amuse eto GEESI.

Se amulo imo-ero fun imuseya Ijoba fun anfaani arwon ara-ilu

10

11 Se afikun iranlowo owo ati imọ-ẹrọ fun ilọsiwaj ati atunse awon nkan amayederun fun anfaani awọn ara ilu.

## Awon Ti Oro Kan

Ijoba Apapo, ipinle ati ibile

Igbimọ iṣakoso idanimọ orilẹ-ede.

Igbimọ fun awon Olopa

Awon Oba ati awonolori elesin.

Ile-Ise Ijoba fun Ibanisoro ati Imo Ero

Awon Ajo Okeere fun Idagbasoke Awujo

Ile-Igbimo Asofin Apapo

Awon Ajo to n pe fun Idagbasoke Awujo



Atunse nipase
Ajo fun Idabobo Eto ati Ilọsiwaju Awọn Obirin (WRAPA)
Pelu ifowosowopo Ile-Ise Ijoba Apapo fun Oro Obinrin
Atilẹyin nipasẹ Ajo MacArthur Foundation.
MacArthur Foundation

